# ITỌSỌNA OBI KAN SI AWỌN IPINYA DIẸDIẸ



## Kaabọ si Itọju fun Awọn ọmọde Tuntun (CNC)

***Kaabọ si eto CNC wa!***

*Lati ran ọmọ rẹ lọwọ lati wa ni ailewu, ati lati gba ọ laaye lati kawe laisi aibalẹ ọkan, o ṣe pataki lati lo akoko diẹ lati ni itunu pẹlu eto ati oṣiṣẹ wa.*

***Nigba miiran awọn ọmọde n ke, lero pe wọn sọnu tabi huwa lile nigba ti awọn obi wọn ba ni lati lọ kuro. Ijaya ipinya bẹẹ jẹ deede—paapaa ti o ba jẹ akoko akọkọ ọmọ rẹ ninu itọju ẹgbẹ. Lati ṣe iranlọwọ fun ẹyin mejeeji ni akoko yii, a n ṣakoso awọn ipinya akọkọ ni pẹkipẹki nipa lilo ipinya diẹdiẹ.***

## Kini ipinya diẹdiẹ?

Ipinya diẹdiẹ tumọsi mimu gbooro aaye ti ipinya laarin obi ati ọmọ bi ọmọ naa ṣe ni irọrun diẹ sii ninu eto naa. O niṣe pẹlu iṣiṣẹ pẹlu oṣiṣẹ eto ati igbaradi ọmọ rẹ fun awọn ipinya akọkọ saaju akoko.

**Ipinya diẹdiẹ:**

- bọwọ fun awọn aini awọn ọmọde,
- ran ọmọ rẹ lọwọ lati ni aabo ati ipamọ,
- ṣe atilẹyin iyipada geerege sinu eto wa, ati
- ṣeto ipele fun awọn ipinya aṣeyọri ati asomọ ti ilera bi ọmọ naa ti ndagba.

Awọn ọmọde ti o ni iberu awọn ipinya akọkọ ni o maa n gba akoko pupọ ki wọn to farabalẹ sinu eto naa, nitori naa jọwọ mura lati duro pẹlu ọmọ rẹ bi o ṣe nilo. Ọmọ kọọkan yatọ, ṣugbọn o ṣe pataki lati ma ṣe ilana naa ni kọmọkọmọ.

## Bawo ni o ṣe n ṣiṣẹ?

**Ṣaaju ki o to bẹrẹ kilaasi:**

- Bi o ba ṣeeṣe, ṣabẹwo si eto wa pẹlu ọmọ rẹ.
- Pẹlu ominira, ba awọn oṣiṣẹ sọrọ nipa ọmọ rẹ, eto naa ati bii wọn ṣe ṣe ilana fun ipinya. Eyi ṣe iranlọwọ fun ọmọ rẹ lati rii oṣiṣẹ bi ailewu ati olugbẹkẹle.
- Bi o ba ṣeeṣe, fihan ọmọ rẹ ibiti iyara-ikawe rẹ yoo wa.

**Awọn ọjọ akọkọ ọmọ rẹ**

- Gbiyanju lati ni ifọkanbalẹ ati ireti.
- Lọsi agbegbe ti o ro pe ọmọ rẹ yoo gbadun julọ ki o sọ fun oṣiṣẹ ohun ti ọmọ rẹ fẹran lati ṣere pẹlu.
- Fọkansi ọmọ rẹ. Ba wọn sọrọ, fi awọn ohun-iṣere han wọn ki o ṣe ere pẹlu wọn.
- Ni itaji si eyikeyi awọn agbegbe miiran ti o le dabi ẹni pe o nifẹsi ki o tẹle itọsọna wọn.
- Wo awọn iṣora lati ọdọ oṣiṣẹ naa.
- Gba ọmọ rẹ niyanju lati ṣere pẹlu awọn ọmọde miiran tabi pẹlu oṣiṣẹ nigba ti wọn ba ṣetan. Bi ko ba dabi pe ọmọ rẹ ti ṣetan, o dara lati duro diẹ si.
- Nigba ti ọmọ rẹ ba ni ṣetan lati ṣere fun ara rẹ tabi pẹlu awọn omiiran, eyi jẹ ami ti o dara pe wọn ti ṣetan lati gbiyanju ipinya wọn akọkọ! Gbiyanju gbe igbesẹ kan sẹhin lati wo.


*Funded by: Immigration, Refugees and Citizenship Canada / Financé par : Immigration, Réfugiés et Citoyenneté Canada*

- Ti ọmọ rẹ ba tẹle ọ lẹsẹkẹsẹ ati pe o dabi ẹni pe o nilo lati wa ni isunmọ rẹ, wọn le mai ṣetan.
- Iyapa ni kikun le gba ọpọ igba fun awọn ọmọde ti o ti ni iriri iwa-ipa ati ibalọkanjẹ.

**Awọn ipinya akọkọ**

Nigba ti iwọ ati oṣiṣẹ rii pe ọmọ rẹ n ṣere daradara ati pe o dabi ẹni ọkan re balẹ, o le bẹrẹ lati lọ kuro ni eto naa fun awọn akoko kukuru.

- Sọ fun ọmọ rẹ pe o nlo si yara itura ati pe iwọ yoo pada wa ni iṣẹju meji.
- Maṣe fi yara silẹ lai sọ fun oṣiṣẹ nipa lilọ rẹ
- Lọ si ibi iyara iyura ki o rii daju pe o pada wa bi o ti sọ.
- Ti ipinya akọkọ yii ba jẹ ọgbẹ fun ọmọ rẹ, wọn le ma ṣetan.

Lẹhin ti ipinya akọkọ lọ daradara, lẹhinna o ti ṣetan lati gbiyanju ipinya keji ti yoo jẹ gun diẹ (iṣẹju 5–15). Ati lẹhinna ẹkẹta, paapaa ipinya gigun (iṣẹju 10–20).

Awọn ipinya kukuru wọnyi kọ ọmọ rẹ ni igbẹkẹle ati pe o ṣe iranlọwọ fun wọn lati ni oye pe iwọ yoo pada wa nigbagbogbo. Fun ipinya kọọkan, rii daju lati:

- Sẹ dédé.
- Sọ fun ọmọ rẹ pe o nlọ.  Iyọjade n ba igbẹkẹle jẹ yoo si mu ki awọn ipinya ọjọ iwaju nira.
- Jeki kiki odabọ rẹ jẹ kukuru niwọnba ki o ni iṣe deede/imọra pẹlu awọn osisẹ nibẹ lati ṣe atilẹyin ọmọ rẹ nigba ti o ba lọ.
- Fọkansi awọn idaniloju rere nigba ti o ba pada wa. Gbiyanju bibeere lọwọ ọmọ rẹ nipa iru awọn ohun-iṣere ti wọn fi ṣere tabi ohun wọn fẹran ti o dara julọ.

Nigba ti ọmọ rẹ ba gbiyanju awọn ipinya kukuru wọnyi laisi wahala ninu pupọ, wọn ti ṣetan fun ọ lati lọ! Nigba ti o kọkọ bẹrẹ n fi ọmọ rẹ silẹ fun gbogbo ipari eto naa, gbiyanju lati jẹ ọkan ninu akọkọ lati wa mu wọn lati mu ero pe iwọ yoo pada wa nigbagbogbo.

**Bi ọmọ mi ba binu nkọ?**

Bi ọmọ rẹ ba tun ni iṣoro, gbiyanju lati maṣe ṣe aniyàn. O le nilo lati lo diẹ ninu akoko si pẹlu ọmọ rẹ ninu eto naa lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati ni aabo ati ifọkanbalẹ. Mimu ọmọlangidi kan tabi aṣọ ibora wa, tabi fifi ibori rẹ tabi aṣọ otutu le ṣe iranlọwọ fun ọmọ rẹ lati ni ifọkanbalẹ diẹ sii.

Awọn oṣiṣẹ eto ti ṣe iranlọwọ ọpọlọpọ awọn idile nipasẹ ilana yii ati pe wọn wa nibẹ lati ṣe itọsọna ati atilẹyin fun ọ.

ATILEHIN TI ITOJU ATI ITEDOSI
TI AWỌN ỌRỌ ISILỌ TI ỌMỌDE

CMAS

*Fun diẹ sii nipa ohun elo eronja obi, ṣabẹwo:*
*www.cmascanada.ca*

Care for Newcomer Children


*Funded by: Immigration, Refugees and Citizenship Canada / Financé par : Immigration, Réfugiés et Citoyenneté Canada*